# IWE SI OLOTU IROHIN YORUBA

### SAMMY-BOY ATI KẸHINDB Ẹ LA BYI YE WA ?

Alagba/ Jọwọ gba mi laye die lati fi ibere mi yi si waju awọn cnia meji yi, Ọgbẹni Sammy Boy ati S A Kẹhinde, Eko nipa Irohin afadun awọn ọmọ Awẹ ti o jade ninu Iwe Irohin 18/2/52.

Ibere na niyi nigbati mo nka rohin Awẹ lọ inu mi dun fun irẹpọ wọn ṣugbọn nigbati mo fẹrẹ ka ọrọ na tan mo wa se akiyesi gbolohun ọrọ yi pe "ẹiyẹ Ogongo wa lati Ogbomọsho lati wo ilu Awẹ." Mo nbere nisisiyi tani ẹiyẹ Ogongo Ogbomọsho ? Enia ni nje bẹ ni tabi ẹiyẹ oko mo fẹ mọ o ?

Olotu mo dupẹ ọkọ oba ki yio ṣe nyin lẹṣẹ. Ẹ o ma leke ṣa a ni

Emi ni
Joseph L. Jokodola
Ọlọrun-ni-mbẹ
NSAWANI
GOLD COAST

### A DUPẸ LỌWỌ OKẸ

Inu mi a dun pupọ ti Olotu ba jẹ gba mi laye lati dupẹ lọwọ Ọgbẹni G O Ọkẹ ti Jos nipa alaye rẹ ti o jade ninu Iwe Irohin Yoruba ti 11/2/52 ati 18/2/52.

Ẹnikẹni ti o ba ka ọrọ Bibeli ti alagba na tọkasi yio mọ daju. daju pe ariwo lasan ni Alfa Akewukewe npa, ati pe alaye G O Ọkẹ fi han pe asọdun Bọlaji Akewukewe ko ba ọrọ Ọlọrun mu rara.

Ẹaiti o ba tẹle ọrọ Akewukewe ṣe ẹsin tabi fi hu iwa yio jinna si ọna igbala ju awọn Keferi paapa lọ, G O Ọkẹ ẹ ku iṣẹ Oluwa o, a si tun nreti ọrọ alaye nyin si i o, ni oruko gbogbo onigbagbọ mo dupẹ lọwọ nyin o.

Emi ni
Joseph Lajide
JEBBA—KUNGU



### AMIYAMỌ BTI RẸ MẸLO

Abiku ọmọ nde ọ l'amu bi ?
Awọn arun wọnyi ha kọ ọmọ rẹ lẹnu bi

AIFERI
ỌRẸRẸ
INU-IWỌ
OSI
IGBONA
IKỌ
IGBẸ-ỌRIN
OTUTU
IBA
JẸDIJEDI

ati oriṣiriṣi awọn arun miran ti ima yọ ọmọde l'ẹnu ni igba EHIN HIHU, lọ ra "YARO" awọ igba arun ọmọde ni fun gbogbo awọn arun ti ima yọ ọmọde l'ẹnu.

"YARO" wa pe meji ni gbogbo ilẹ Nigeria.

Ki iwọ ki o si i pe orukọ "YARO" ni o wa lara igo sa ki a ma ba ta adamọdi egbogi miran fun.

### IGBEYAWO BAYỌDE LARINRIN

ỌBA-AKOKO— Ni ọjọ Abamẹta ti nṣe ọjọ kọkandinlogun oṣu kini ọdun yi ni Bayọde Arogbẹshin Obilẹgbinrinmilodi ṣe igbeyawo omidan Eunice Ọlarinde.

Igbeyawo na larinrin pupọpupọ. Igbeyawo na larinrin gbajumọ pọ nibẹ Ariye, inawo ati gbajumọ pọ nibẹ Awọn ti o wa sibi ere igbeyawo na to ẹgbẹrin lọkunrin ati lobinrin Ere sakara ni nwọn fi ṣere igbeyawo ni ọjọ na nwọn niuu bi arira, awọn ọkọ iyawo njo bi okoto oriṣiriṣi aṣọ ni nwọn fi nparada ọjọ na. Apoti ọti bia ko niye ọmọde tagba lo mu ọti yo ọjọ na.

Awọn alaga pataki ni ọjọ na ni wọnyi:- Awọn Ọgbẹni M. B, Ọdanigbo, S, Kẹhinde, Tailor, Yisa Lawani, Yaya, Millar ati Jimọ Akinbọla, awọn alaga wọnyi na owo bi ẹlẹda lọjọ na.

Orukọ awọn ti o tun wa si bi ere na ni awọn Ọgbẹni Jonathan Ọlayanju, Alfred Adeyẹmi, S. Ọladele, Adeniyi, Iya Afin Ajikẹ Awọn ogbẹni J. Ọla. Aruna Akọwe ọkọ iyawo. Buraimọ Dede Amadu W. Dayọ, Ezekiel Adewunmi, Adunbi Tailor. Agidi Lawal, Clement Adejimọla Taiwo, Jọgodọ, Orubu, Oluwakẹmiaircre, E Abẹbi.

Ki Oluwa Olodunmare ṣeda iyawo na ni alabiyamọ, ki o si fi re kari o Amin.

## GBON IKORA NA KURO
(ELEYI NI ỌNA T'OYA TOSIRỤRUN)



## MENTHOLATUM



"Metholatum" Fifipara a maa mu ara didun ati irora kuro werewere bi idan. Iwọ yio mọ atura rẹ lara, itura yio de lẹsẹkanna ti o ba ti fi pa ibiti o ndun ẹ. "Mentholatum" ko nira rara lati lo, Iwọ ṣa ti fi pa ibiti o ndun ẹ ? Fipa ibẹ gan an, irora na a si lọ. Bi iwọ ba tete lọ ra "Mentholatum" itura yio si de si ẹ. lọ tete ra idẹ (jar) tabi agolo "Metholatum" kan loni-

Bere fun Mentholatum gan an. Eyiti o jẹ pe awọn Mentholatum Co. Ltd., (Est. 1889) Slough, England nikan ni nwọn nṣe e

## AKIYESI PATAKI

Eyi ni lati fi kede fun gbogbo ẹnyin onkawe wa wipe ti ẹ ba nkọwe si wa ki ẹ ma kọ ọ yanju, nitoripe ọpọlọpọ ni awọn iwe (Letters and News) ti a nri gba lati idalẹ, ti o si jẹ wipe idaji ni a o ri ka ninu rẹ.

Nipa bayi gbogbo anfani ti iba ti irufẹ inu iwe bẹ jade ti pari sibẹ niyẹn, nigbati a ko le tẹ jade fun gbogbo aiye ka.

Fun awọn ti o nbinu pe iwe nwọn ko tete njade tun fi eyi ṣe alaye fun nyin pe ohun ti o nfa iyẹn nipe iwe ti a nri gba ni arin ọsẹ kan le ni igba (200)

A ki gbogbo nyin patapata Ajinde ara o ma jẹ e

OLOTU

## E ma a polowo Ọja nyin sinu iwe "IROHIN YORUBA"

Ẹ o si ri iyatọ larin bi ẹ ti ti ni onibara si ati bi e ti tun bere si ti ni si lati isisiyi lọ.

